**ỌJA TITUN**
Iwe Iṣegun Ajẹ 4/6d
Iwe Ala nla 7/6d
Iṣedalẹ Yoruba 4/6d
Turari iṣegun Ajẹ 10/6d
Iwe Afọṣẹ 4/6d
Kọ iwe si Manager, SHOYINKA, 6,O jo Road, Odu-Abọrẹ, Mushin.

# ỊROHIN ỊMỌLẸ

MOTTO: IMỌLẸ DE, OKUNKUN PARADA.

**FUN TITA**
Iwe Itan Igbeyawo Oṣupa ati Ifẹolitọ ati bi Oṣupa ṣe ntan imọlẹ rẹ sori aiye Oyinmọmọ ni 5/- fun ẹyọkan ati Iwe Adura Akanṣe ati Apẹrẹ ile Aiye 2/6d. Kọwe si:-
*Lawrence Bamhgose*
28, Upper Offin Lane, Lagos.

VOL. VI No. 353 MONDAY OCTOBER 22 — OCTOBER 28 1962 KỌBỌ MEJI (2d)

# AWỌN ARA EKO PEGEDE, NWỌN FI GBỌRỌ JẸ'KA!!!

Idunnu subu l'ayọ, ayọ wa subu l'oyin, ni abayọri IBO ti gbogbo awọn enia ilu Eko di fun awọn Asoju Igbimọ Ijọba Ibilẹ Eko (Lagos Town Council) yika gbogbo agbegbe ilu Eko, Yaba, Ebute-metta, Apapa, Surulere, Abule Ijẹsha, Makoko ati Ikoyi ni owurọ ọjọ Aje ti iṣe ọjọ kẹdogun oṣu yi.



*IYAAFIN E. O. FẸMI PEARSE*

Ni deede agogo mẹjọ owuro ti nwọn bẹrẹ idibo na, nwọn si pari rẹ ni agogo mẹfa irọlẹ. Lẹsẹkẹsẹ ti nwọn pari idibo yi ni awọn Akọwe Oluka-ibo ba bẹrẹsi kika rẹ.

AYỌRI SI IBO

Ni deede agogo mẹwa alẹ ni a ti bẹrẹsi gbọ irohin abayọri ibo na pe Ẹgbẹ Afẹnifẹre mẹta, Ẹgbẹ Alakukọ meji, Ẹgbẹ Olomi "Bokodaya" ati awọn ti ko faramọ Ẹgbẹ kankan "Bakodaya"

Nigbati o tun di agogo kan ku iṣẹju mẹdogun (12: 55 a.m.) a tun gbọ irohin lati inu Ẹrọ-Asọrọmagbesi pe, Ẹgbẹ Afẹnifẹre mẹsan, Ẹgbẹ Alakukọ meje, awọn Ẹgbẹ yoku "Bakodaya."



*ỌGBẸNI J. A. ỌDẸKU*
*Igbakeji Akọwe Agba Ẹgbẹ Afẹnifẹre.*

Nigbati nwọn yọri kika ibo na, a gbọ irohin lati inu Ẹrọ Asọrọmagbesi ni kutukutu owurọ ọjọ Iṣẹgun ti iṣe ọjọ kẹrindinlogun oṣu yi ni deede agogo mẹfa wipe, aye ijoko mẹtadinlọgbọn ni Ẹgbẹ Afẹnifẹre (A. G.) gba ninu aye ijoko mejilelogoji ti ILE-IGBIMỌ na ni Ẹgbẹ Alakukọ (N.C.N.C.) si ko aye-ijoko mẹdogun yoku.

NA ỌMỌ MI FUN MI

Abayọri idibo yi fi han gẹgẹbi owe Yoruba ti o sọ bayi wipe:- "Na ọmọ mi fun mi, ki ide inu Ọlọmọ" Bẹẹ na ni nitootọ, awọn ara Eko ko fi ọrọ Ẹgbẹ Afẹnifẹre ṣere, nwọn ko si jẹ pada lẹhin wọn, nitoripe, nwọn mọ riri oniruru iṣẹ ribiribi ti nwọn ti ṣe fun anfani ilu Eko, nigbati Igbimọ na wa ni ikawọ wọn tẹlẹri.

Ẹ KU ORI RE O

A ki gbogbo ẹnyin Asoju Igbimọ na ti o ṣe orire lati jagun-wọle Igbimọ na, ki Ọlọrun Alanu mu ẹsẹ gbogbo nyin duro, ki o si fi ọna han nyin lati ma a ṣe eto Ijọba rere fun idagbasoke ilu Eko ati gbogbo enia inu rẹ.

CALL AT

**The Classical Saloon**

365, Herbert Macaulay St., Yaba. (Near St. Agnes Bus Stop.

*For all your hairdressing & Styling, Artificial hair (New and Renewal) Sewing and Machine Knitting.*

Every satisfaction and speed guaranteed

**Mrs. C. A. Kupoluyi**
*(The London trained expert)*

## Ọkunrin kan fi owo Ijọba ta tẹtẹ

IBINNI:- Kẹke pamọ gbogbo enia lẹnu ninu ile-ẹjọ giga Ibinni nigbati Ọdaran kan sọ ṣako niwaju adajọ pe owo Ijọba ni on fi ita tẹtẹ.

Awọn Ọlọpa ti o ba Ọdaran na, John Atalegbe, ẹni Ọdun mejidinlogun, ti o ngbe Uzeba ni agbegbe Ibinni ṣejọ, ṣe alaye niwaju Oloye M. A. Behgo, adajọ ile-ẹjọ pe, Ọdaran na jẹ Ọga ile-ifiweranṣẹ, o si gba awọn Stamp ti iye owo rẹ jẹ pọnun marundinladọta (£45) fun tita fun awọn enia.

Ṣugbọn nigbati Ọga-agba ile-ifiweranṣẹ de lati ṣe iṣiro, Owo Ọdaran na din pọnun mọkandinlọgbọn ṣile marun ati epinni (£29 : 5s 5½d nitoripe o ko owo na fun awọn Onijibiti lati sọ Owo na di pupọ.

Ọdaran na gba wipe on jẹbi, ṣugbọn o bẹ adajọ ki o dariji on. Lẹsẹkẹsẹ ti adajọ na fun un lesi 'pe, on ki yio dari jin ẹniti o rẹ Ijọba jẹ; nitorina ki Ọdaran na lọ fi ẹwọn Oṣu mẹta jura.

## Eko gba'yi !



*ỌMỌ OBA "ẸRUKOBODO"*
Onitan Iṣẹdalẹ Yoruba

Ẹ ku eto idibo Eko, Ẹniti, a pe-tapero pe ka dojuẹbolẹ npele lo tun npele.

Tete ra Iwe Irohin Imọlẹ ọsẹ ti mbọ.

RA

**Yoruba Challenge**

November — December

*Fun*

**Aworan Igboro Eko KERESIMESI**

*ATI*

*Itan otitọ aladun nitl "Oloriṣ ti O Pade Olugbala."*

*Iwe aloju ewe 24 yi ko le'wo*

**4d** pere ni iwe kan

# KEREO! AKIYESI PATAKI!!

Awa na le jeri wipe Ojulowo haunhaun Egbogi gidi ni LEOPILLS, awa na nlo ni Gold Coast (Ankara Ghana) pelu, meji re ko si ninu gbogbo orisirisi Egbogi, kakiri Ilu Naijiria




## Irohin kakiri Igboro Ilu Eko

Be ua ni ewe ni gboro Ilu Eko, Irohin ti o wa lenu gbogbo enia l'omode l'agba ni asiko yi ti nwon si fi se oro ati orin larin ara won je nipa Egbogi Jamani elokiki yi ti nwon npe ni LEOPILLS.

Imoran awon Dokita Oyinbo ti nwon nse iwadi Egbogi LEOPILLS yi kan so wipe bi o ti lagbara to, ti o je Ojulowo giriki ati atamatase fun iwosan "JEDIJEDI" bi o ti wu ki ojo re pe to bena ni awon le tun fi owo soya tabi se ileri fun gbogbo awon ti amodi tabi Iju, Igbe sise, tabi aiko ri igbonse dede, Inu rirun nigbakugba ara wiwo. Esanri. Ehin didun, Oju sisan, tabi aiko riran kedere kokoro buruku lara, Osi inu Onigbameji ati orisirisi arun miran gbogbo pelu "Wipe" awon yio ri alafia ni kiakia ti nwon ba nlo Egbogi LEOPILLS nitoripe o si tun ma tun eje se lara enia nipa siso di otun patapata.

ṢE IRANTI PE ALAFIA L'OGUN ORO, IJAFARA SI LEWU PELU (POSTAGE 1/9d)

**IYE OWO EGBOGI LEOPILLS:-** Igo nla sile mefa abo (6/6d) pere ni, Igo kekere sile meta abo (3/6d) pere ni.

Bere Ojulowo Egbogi miran fun orisirisi Amodi ti o ba fe ni Sobu awon:—

**Waterloo Medicine Stores**
8. Palm Church Street, P. O. Box. 333. Lagos Nigeria Phone 22878, ati pelu ni Sobu awon arabinrin Mrs. C. O Babajide near Health office Ibadan ati ni A b i m b o la Medicine Store B29 Okesha Street Ilesha. Bisale Medicine Stores, British & Foreign Medicine (Dealer) S. W. 6/458 AGBOKOJO STREET, IBADAN N o

AKIYESI.- Ri daju gbamgba wipe Sobu ti nwon nta la gbe ranse lo ra, bi be ko awon elomiran yio fi ERU lo ta Adamodi tabi orisi omiran fun o o, mase gba rara o.



# Akiyesi Pataki

Lehin nkan bi odun mefa sehin ti nwon ko se wa mo rara, egbogi oju na tun wo ileyi. Bere:—

# "COLLYRIO PAGLIANO"

Bi amodi tabi aisan "OJU DIDUN" ba nyo o lenu nigbakugba tabi fun ojo to ti pe jojo, ye EJE ARA RE WO nipa lilo egbogi atata ti o daju fun eje ara RICHALET lehin na ewe, ki o si ra egbogi ti awon ara ilu Tatambulu (Italy) se lati ma a kan si oju na pelu, ti a npe ni "COLLYRIO PAGLIANO" fun oju didun, Meji re ko si ni igbero ilu Naijiria.

Se iranti wipe oju ni oaba ara o, ijafara si lewu pelu Bere ni Sobu awon Olori egbogi Jamani igboro Eko ti nwon npe ni:—

**Waterloo Medicine Stores**
**Continental Medicine Specialist**
8, Palm church Street, Lagos P. O. Box 333,
Phone :22878, Lagos Nigeria. (Oja ita Faji)


# ITUMO ALA

Lati owo:- Amos Alore

1. Ti o ba la ala wipe, enikan gun esin re nwon yio gba omo odo re laipe.
2. Ti o ba la ala wipe, o ri okun ti nru soke, Oluware yio bo sinu idamu aiye.
3. Ti o ba la ala wipe, o ri agbado loju orun, oluware yio di olowo, tabi ti o ba sowo kan yio jere lopolopo.
4. Ti o ba la ala ri iledu, oluware yio ni ibanuje, aibale okan ati fitina aiye yio po fun oluware.
5. Bi o ba la ala pe, ile jio si isale ti o ba je onisowo adanu nla mbe fun oluware.
6. Ti o ba la ala wipe, o je akara-agbado, ohun rere ni fun talaka sugbon ifasehin ni fun olowo.
7. Bi obinrin ba la ala wipe on nse nkan-osu l'oju orun, ki o mo wipe on nse ise kan ti Olorun ko fe ni asiko na.
8. Bi obinrin ba la ala wipe on pari nkan osu ni oju orun, yio ni oyun laipe
9. Bi obinrin ba ni oyun, ti o si la ala wipe o nse nkan osu, omokunrin ni yio bi.
10. Eniti o ba la ala wipe on ngbe kanga, ki o sora, iyawo re yio se ijamba fun un ninu odun na.

O tun di ose ti mbo o.

# YE IRAWO RE WO

Eyi ni awon nkan ti yio sele si o larin ose yi.

AQUAIRS (Jan 20 - Feb 18) Mase lo akoko re lasan si awon nkan tiko nidi. Orire wa fun o larin ose yi.

PISCES (Feb 19 - Mar 20) O di owo re larin ose yi, ero rere yio wa fun o lenu ise, awon enia atata yio se iranlowo fun o.

AIRES (March 21 - April 19) Oke isoro wa fun o larin ose yi, sora pelu oro enu re larin awon enia.

TARIUS (Apl 20 - May 20) Ilosiwaju wa fun o larin ose yi ti o ba rin mo awon enia atata.

GEMINI (May 21 - June 20) Anfani kan ti yio yo si o lowo, mase jeki o bo ti o ba se adehun mase jeki o ye, orire wa fun o lodo awon obinrin.

CANCER (June 21 - July 20) Oro kan yio mu ibinu wa fun o nitorina mase se nkan titun kan ti yio da okan re ru.

LEO (July 21 - Aug 22) Isoro inawo ti o wa fun o yio dopin. o si gbo irohin rere kan.

VIRGO (Aug 23 - Sept 22) Mase siyemeji si ara re, ki o si so enu re pelu oro egan.

LIBRA (23 - Sept 22) Ere pupo wa fun o lati se adehun, o si bori awon idiwo kan ti o ti duro si oju ona re. Ose yi dara lati se ibewo awon ore.

SCORPIO (Oct 23 - Nov) Aseyori ise wa fun o l'ose yi, sugbon ki ise lesekese, nitorina mase lo akoko ati agbara re si nkan ti ko nidi.

SAGITTARIUS (Nov 22 - Dec. 21) Gbogbo nkan ti o ba se ni yio ma a se deede, papa lodo Obinrin, sugbon se eto fun ojo iwaju.

CAPRICORN (Dec 22 - Jan 19) Nkan pataki ti o wa fun o larin ose yi ko ti daju, nitorina, so agogo gbe je e m'owo.

# Alo ...
# Alo ...

1. Orisa ile a... mode i a g... juba fun u... la icjumo
2. Ore meji n... yara won... iku ba de
3. Ofofo ile a... gbogbo wa... eniti ko ta... pe nile aiye
4. Kiiki Oloko... kiiki Olo... ikunpa,... koko. to o:
5. Enia meji ja... pari re fu... ko pari,... ma fohun... re o
6. Emo eti oku... maiepo
7. Oku ku, a t... oku di oku...
8. Erin ku mag... je. Efon ku... du fi je, m... ku ko reni...
9. Angun Iyan... njo

# Itumo A...

1. Onje
2. Ojiji enia
3. Oju
4. Aparo
5. Owo
6. Ina ori
7. Koriko Iko...
8. Isasun-Ob...
9. Omu

Iwo...
be...
f'ow...

# IDIJE ! IDIJE !!

A fi eyi kede fun gbogbo awon Onkawe IROHIN IMOLE ati awon Omo karo-o-jire pe a nse

## ITAN LEDE YORUBA

Eyiti enikeni ko ti te jade ninu iwe ri tabi ti nwon ko ti so lori ero Redio ri; enikeni ti o ba si beri yio gba:—

**PONUN KAN ŞILE KAN (£1 : 1/-)**

*AKIYESI*– Ko itan re ki o han tekete, ti eniti ko ba han ao fa a ya ni, ki o si mo dajudaju pe ko ni ipin ninu Idije na ITAN eniti o ba si daraju ni ao te jade ninu IWE IROHIN IMOLE yi, ao si fi Ponun kan Şile kan (£1 : 1/-) (Postal Order) ranse si i. A ko ko otnode tabi aghaiagba.

Fi Stamp Toro **(3D)** ranse fun gbigbe Ponun kan Şile kan **£1** :1/-) ti o ba je pada si o, ki o ge ibiti Idije yi wa, ki o si fi ranse pelu Stamp Toro re si wa. Enikeni ti ko ba ge Idije tire ranse si wa, ti o ba je owo na a ko ni fi ranse si i, a ko si ni fun un ni Stamp Toro re.

Idije yi yio pari ni ojo kini osu kejila odun yi. Ao te itan eniti o ba dara jade ni ojo keta osu kejila odun yi (3/12/62).

*ORUKO* ______________________

*IBUGBE* ______________________

______________________

Fi itan re ranse si:–

**OLOTU IROHIN IMOLE**

16, Bamgbose Street, Lagos.



BERE OJULOWO EGBOGI AWON FARANSE TI A NPE NI:-

# "UROXAL"



Fun Itoju tabi fifo Apo Ile Ito Kidney-Blader fun Okunrin ati Obinrin bi awon amodi wonyi ba nyo o lenu Ehin didun eri ile ito tabi ito-jijo enia, ito riru rukuruke pipon tabi rirun, lakuregbe Ibaradi wiwo, orunkun, owo, ese Ejika wiwu tabi riro.

Ara sisan, titobiju aiko le gbe ara kankan tabi kiakia didaji loru sigbakugba, ati orisirisi awon aisan tabi amodi ba wonyi ni egbogi ajebidan yi yio wo san lara re ni kiakia ti al-fia yio si de si o. Meji re ko si ni ilu Na ira nitorina sora ki awon o ra tabi awon oni robirobi ma ta orisi omiran ti ko ni lari fun o ma se gba a rara o! Owo re je şile mejo abo (8/6d) owo oko şile meji abo (2/6d) bere egbogi yi ni sobu awon Saro ti nwon npe ni:–

NIGERIAN MEDICINE STORES
4 TINUBU STREET, LAGOS PHONE:- 20278.

**Waterloo Medicine Stores,**
**8, Palmchurch Street, Lagos,**
**Phone: 22878 Nigerian, (Oja ita Faji)**

ADEDUN CHEMISTS
48, WAKEMAN STREET, YABA. PHONE: 22878

ATI NI AWON SOBU IBADAN:–
ISE OLODUMARE DISPENSARY OKE-BOLA





**o ha lè gbe iyawo bi? Iwo le se e laipe lo titi bi o ba bère lati ma wo pamo ni odo Barclays nisiyi!**

Latigba degba ni ki o ma f'owo pamo, ki o si toju re s'ile ipamo owo. Fi okàn tàn Barclays nipa itoju owo re, eyiti iwo yio si gbà pada yio si ju iye ti o fisibe lo! *Lo bère* ni banki ti Barclays tombe nitosi odo re nipa fifi owo re pamo. Awon ni yio fun o ni imoràn ati iranlowo to darajulo.

**"IGBEYAWO NA"**

Barclays Bank ti se awon aworan sinima eyiti [illegible] lati ma wo, boya iwo papa ti ri tele. Aworan ti anpe ni "IGBEYAWO NA" [illegible] odomokunrin kan to fe gbe arewa omidan ti anpe ni Alake n'iyawo. Sugbon baba Alake ko gba!



Odomokunrin na ti oruko re nje Kwesi [illegible] lati ma f'owo pamo bi agbara re ti mo. Nigbati o si pada, [illegible] o bère si f'owo pamo sinu banki ti Barclays. Larin akoko yi, nkan lo ku ki okunrin buburu kan ji olufe re gbe lo.



Sugbon gbogbo [illegible] nikehin nigbati Kwesi mu gbogbo [illegible] pelu okunrin buburu [illegible] owo re tombe ni Barclays Bank.

Iwo na gbodo bère lati ma f'owo pamo, nitoripe igbeyawo ama na enia l'owo lopolopo!

**BARCLAYS BANK DCO**

## Jesu Kristi ni Olugbala gbogbo Aiye

*Lati owo:- ALUFA SIKIRU, AGEGE*

AH! TANI ONIDAJO AIYE?

Inu mi yio dun lati se alaye fun gbogbo aiye, gbogbo wa la fe mo Eniti yio se idajo Aiye, o ye ki a mo Onidajo aiye ati pe Tani yio se idajo aiye? Jesu ni Bibeli j'eri si pe yio se idajo aiye, eri to daju si wa.

Bibeli so fun wa gbangba pe, onidajo aiye ni JESU, o si daju pe otito ni niwaju Jesu ni ao ko gbogbo aiye jo si Alukurani so gbangba pe Jesu ni onidajo aiye. Mo tun bere pe tani onidajo aiye? Nitoripe JESU ni onidajo otito ati ododo on si ni Olorun fi se onidajo Aiye.

E jowo e gbo asotele ninu: 2, TIMOTIU 4 ESE 1. O ka bayi:- Nitorina mo pa lase fun o niwaju Olorun ati Kiristi Jesu Eniti yio se idajo Alaye ati Oku.

Ati nitori ifarahan Re ati ijoba Re, gbogbo eri yi fihan gbangba pe JESU ni yio se onidajo Alaye ati Oku. Alukurani jeri si oro yi ninu Sura 3 Aya 48–51 Olorun pase lati mu JESU jade lati inu Maria nipa agbara Emi-Mimo. Oloran yio se ni Iranse pataki kan fun awon enia, Olorun yio si fun un ni Agbara lati ma a la oju awon Afoju, lati gbe Aro dide ati lati ji awon Oku dide kuro ni ipo Oku.

Mo lero wipe gbogbo nyin ni yio gba pelu mi pe JESU ni onidajo Aiye.

E gbo Asotele miran ninu Ise Aposteli ori 16 Ese 42-43, O ka bayi pe:- "O si pa lase fun wa lati wasu fun awon enia ati lati jeri pe, on li Olorun yan lati se onidajo aye ati oku. On ni gbogbo awon yio jeri si pe nipa se Oruko re ni gbogbo aiye yio ri imu kuro ese" Gbogbo nyin ni oo gba pelu pe JESU ni onidajo aiye.

E gbo asotele miran ki e le mo pe kosi onidajo kan a fi JESU nikan. E gbo ohun ti JESU wi ninu Mattiu 28 Ese 18. O ka bayi:- "JESU si wa, o si so fun awon omo Ehin re wipe gbogbo agbara li Orun ati li Aiye li a ti fi fun mi" Gbogbo nyin ni oo gba pelu mi pe onidajo Aiye ni JESU.

## U. A. C. fi Naijiria han gbogbo Aiye

EKO:- Ile-ise U. A. C. yio se ifihan awon oniruru ise owo fun idagba soke Naijiria ninu ago won, ninu ifihan ise-owo.

Ohun pataki ti awon onisowo U. A. C. yi fi han ni "Aiye nwo Naijiria nisisiyi" ti nwon se lati fi han gbogbo agbaiye nipa ohun ti o se pataki nipa eto-esunna owo ati idagbasoke owo ni arin ilu.

Gbogbo nkan ti o wa laye awon onisowo U. A. C. fi ireti osiwaju ise rere ti awon osise Naijiria nse han kedere.


## KERE O!

**Kurani L'ede Yoruba TI DE**

A nta Kurani Ogbon-Lau ti a se ni Larubawa ati itumo re l'ede Yoruba, O wolo fun enikeni.

25/- Postage 1/6d

Iwe Egbogi iwosan Ataiyebaiye, o kun fun Awure, a le ri itumo ala ati ohun ti o le runiloju ninu Odu merindilogun ninu iwe kanna.

**10/6d Postage 9d**

*TETE FI OWO TIRE KANSE SI:—*

ESAN KOGBOGUN SERVICE

*8, Idumagbo Avenue, Lagos, Nigeria.*



## Akiyesi Pataki

**Sengovan Tablets! Sengovan Tablets!!**




SENGOVAN TABLET:- Je ajidewe egbogi fun awon agbalagba ati ilera ati gegebi Omokunrin.

SENGOVAN:- Je okan pataki ti a se iwadi ni ilu Okere ni ile Jamani lowo okan ninu awon Ojogbon Onisegun Aremo ti ilu Western Jamani fun are ara eyiti ojo ori re to Ogoji si Ogorin odun (40-80 years).

SENGOVAN:- Je egbogi ti o ti wa lojo pipe fun anfani awon agbalagba ilu Jamani ki a to se amuwa re si ilu Naijiria Ajebidan ni ogun yi.

**Irohin ko to Afojuba**

Bere:- A o ri lowo awon Onisegun (Doctor) Naijiria

Hassan Commercial Medicine Stores
26, Bishop Street Lagos.
Phone: 23745 Lagos.



# IBI IJOKO AWAMOTO INU AUSTIN S 200 DARA TOBE TO FI NMU ARE AWAMOTO DINKU PUPOPUPO O NMU MOTO-WIWA RORUN PELU AISI EWU!



Moto Austin to lagbara yi tunbo nse alekun iwa-moto laisewu nitoripe a ti see dara tobe, eyiti yio seki ise re jafafa siwaju si i. ki ere si ma wole pupo fun o. Moto S itis T 200 ni inu fife, to si bale fun eru kiko; jigi iwaju re lagbara, o si njeki enia riran dada; ojuferese re njeki moto se wa fehinrin laisi e u Bere pe ki awa u wo ki o ri i.

**AUSTIN S 200**

SCOA Motors


*Printed and Published by MODUPE PRINTING PRESS 16, Bamgbose Street, P. O. Box 1495, Phone 21985, Lagos Olotu: E. A. Adeniji 24, Oluyide Street, Odo—Abore Mushin.*